**ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU**

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**ÈTÒ ÌPÀDÉ AGBÁRA GBỌ́DỌ̀ PÀRỌ̀ ỌWỌ́**

**ÌTUSÍLẸ̀ TO JÌNLẸ̀ (APÁ KEJÌ)**

**OṢÙ KÁRÙN, ỌDÚN 2024**

Ìwé Mímọ́ kíkà: Márkù 9

Ìjẹ́wọ́: Lúkù 4:18

## ORIN ÌYÌN ÀTI ÌJỌ́SÌN TÍ Ó L'ÁGBÁRA

1. Ọlọ́run, dìde, kí Ó sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìṣọ́ji, bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ọlọ́run, jẹ́ kí agbára àláfíà àti itẹ̀síwájú, ṣíji bo orílẹ̀-èdè yìí, ní orúkọ Jésù.
4. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fún wa ní àwọn olórí tó bẹ̀rù Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo àjàgà sátánì nínú ayé mi, fọ́, ní orúkọ Jésù.
6. Gbogbo ipá oludènà búburú, tó n gbógun lòdì sí mi, túká nípa iná, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo iṣẹ́ àjẹ́ lórí àṣeyọrí mi, fọ́, ní orúkọ Jésù.
8. Gbogbo èmi-ni-mo-ní òkùnkùn lórí ayé mi, fọ́, ní orúkọ Jésù.
9. Gbogbo igi ìkùnà nínú ìran mọ̀lẹ́bí mi, di gígé dànù, ní orúkọ Jésù.
10. Gbogbo májẹ̀mú búburú tó n ṣiṣẹ́ lòdì sí mi, fọ́, ní orúkọ Jésù.
11. Gbogbo ìwé ẹ̀rí búburú tó lòdì sí ayé mi, jórun nípa iná, ní orúkọ Jésù.
12. Gbogbo àṣẹ àjẹ́ lórí ayé mi, fọ́, ní orúkọ Jésù.
13. Gbogbo ègún gbèdéke nínú ayé mi, parun nípa iná, ní orúkọ Jésù.

14. Gbogbo ìtàkùn béélísébùbù tí wọ́n ṣe sórí ayé mi, ká kúrò, ní orúkọ Jésù.
15. Gbogbo àsọtẹ́lẹ̀ sátánì lòdì sí ayànmọ́ mi, di asán, ní orúkọ Jésù.
16. Gbogbo ọ̀pá-ẹ̀yìn àìrójúrere, fọ́, ní orúkọ Jésù.
17. Gbogbo ẹnubọ̀dè ìdádúró búburú, fọ́, ní orúkọ Jésù.
18. Àwọn olùrànlọ́wọ́ tó n pòórá, ẹ farahàn padà láti gbé ayànmọ́ mi lọsíwájú, ní orúkọ Jésù.
19. Ìwọ agbára ṣíṣe làálà lásán, kú, ní orúkọ Jésù.
20. Agbára iṣẹ́ takun-takun, tí wọ́n yàn lòdì sí ayé mi, kú, ní orúkọ Jésù.
21. Ifòròróyàn fún alàjá tó n mú ìyípadà rere wá, bàlé ayé mi, ní orúkọ Jésù.
22. Ọlọ́run, dìde, kí O sì dààmú ìkà, ní orúkọ Jésù.
23. Ibùdó agbára àjẹ́ ní ìlú abínibí mi, kú, ní orúkọ Jésù.
24. Ọlọ́run dìde, kí O sì gé dànù gbogbo ìránṣẹ́ òkùnkùn tó n pe ayé mi sínú odù ìyówù, ní orúkọ Jésù.
25. Ìwọ agbára Ọlọ́run, ṣàwárí, kí O sì ṣe ìparun fún gbogbo ìkòkò t'ẹ̀mí tí wọ́n yàn lòdì sí ayé mi, ní orúkọ Jésù.
26. Ìwọ iṣẹ̀dá, dìde nínú ogun lòdi sí gbogbo ìránṣẹ́ òkùnkùn tí wọ́n yàn ti ayé mi, ní orúkọ Jésù.
27. Ìpìlẹ̀ làásígbò nínú ìgbéyàwó, fọ́, ní orúkọ Jésù.
28. Nípa agbára tí ó jẹ́ kí Fáráò rì ì, jẹ́ kí àwọn iṣòro olóríkunkun mí kú, ní orúkọ Jésù.
29. Nípa agbára tó dójútì Gòlíátì, Olúwa, jẹ́ kí àwọn iṣòro olóríkunkun mí kú, ní orúkọ Jésù.
30. Gbogbo ògèdè àjẹ́ lòdì sí ayànmọ́ mi, kú, ní orúkọ Jésù.
31. Ẹ̀yin ángẹ́lì Ọlọ́run, ẹ tú gbogbo àwọn tó n pète lòdì sí ayànmọ́ mi, ní orúkọ Jésù.
32. Ìwọ ẹ̀rùjẹ̀jẹ̀ òru, túká níwájú mi, ní orúkọ Jésù.
33. Mo dojúkọ gbogbo ìpèníjà àjẹ́ nípa agbára Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
34. Mo fagilé gbogbo ohun ìjà ìjákulẹ̀, ní orúkọ Jésù.

35. Iná Ọlọ́run, tú ìfọ́jú àti òkùnkùn ká nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
36. Gbogbo ìgbálẹ̀ àjẹ́ tó n gbá àwọn ibùkún mi dànù, kú, ní orúkọ Jésù.
37. Gbogbo ìdókowò sátánì nínú ayé mi, ṣòfò dànù, ní orúkọ Jésù.
38. Ètò sátánì fún ayé mi, pòórá, ní orúkọ Jésù.
39. Olúwa, jẹ́ kí àyíká mi gbóná jù fún ọ̀tá ìkọ̀kọ̀ ìyówù, ní orúkọ Jésù.
40. Olúwa, jẹ́ kí ìmọ́lẹ̀ Rẹ tú àṣírí gbogbo àgbékalẹ̀ búburú tó farasìn, tí wọ́n gbìn yí ayé mi ká, ní orúkọ Jésù.